**MEMORIAL HERMANN HEALTH SYSTEM**
**ÒFIN**

**ÀKỌLÉ ÒFIN:** Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà

**DÉÈTÌ ÀTẸ̀JÁDE:** 03/19/2018
**Ẹ̀YÀ:** 1

---

## ÈRÈDÍ ÒFIN:

Òfin yìí fi ìdí àwọn ìlànà tó mọ́gbọ́nwá múlẹ̀ nípa gbígba àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsan, pẹ̀lú àwọn ìṣe tí Memorial Hermann Health System ("MHHS") le ṣe tàbí bíbẹ àwọn aṣojú gbígbà ode lọ́wẹ̀.

## ÌWÒYE:

Òfin yìí kan gbogbo ohun èlò ilé-ìwòsàn tó ni àṣẹ ìjọba 501(c)(3) èyítí MHHS ń ṣe tí a sì bò nípasẹ̀ MHHS Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó ("FAP"), èyítí ó kan:

Memorial Hermann Greater Heights Hospital
Memorial Hermann Katy Hospital
Memorial Hermann Memorial City Medical Center
Memorial Hermann - Texas Medical Center
- Memorial Hermann Cypress Hospital
- Memorial Hermann Orthopedic àti Spine Hospital

Memorial Hermann Northeast Hospital
Memorial Hermann Rehabilitation Hospital Katy, L.L.C.
Memorial Hermann Southeast Hospital
- Memorial Hermann Pearland Hospital

Memorial Hermann Southwest Hospital
Memorial Hermann Sugar Land Hospital
Memorial Hermann The Woodlands Medical Center
TIRR Memorial Hermann

MHHS ń ṣiṣẹ́ àwọn gbọ̀ngán àwòrán aláìsan òde, ògùn òyìnbó eré ìdárayá àti àwọn gbọ̀ngán ibi ìtọ́jú, àti àwọn gbọ̀ngán pajáwìrì bíi èyí tó dá lórí olùpèsè, àwọn ẹ̀ka iṣẹ́ aláìsan ode fún àwọn ilé-ìwòsàn tí a dárúkọ lókè, wọ́n sì wà lábẹ́ òfin yìí.

## GBÓLÓHÙN ÒFIN:

1. Ó jẹ́ òfin MHHS àti àwọn ilé-iṣẹ́ tó ṣiṣẹ́pọ̀ tó wà lábẹ́ FAP láti lépa gbígba ìyókù owó aláìsàn láti ọwọ́ àwọn aláìsàn tó ní agbára láti sanwó fún àwọn iṣẹ́. Òfin yìí ṣàlàyé àwọn ìṣe tí MHHS le ṣe láti gba ìdíyelé ilé-ìwòsan àti/tàbí àwọn ìdíyelé míràn fún àwọn iṣẹ́ tí a pèsè fún àwọn aláìsàn MHHS. Òfin náà tún ṣàlàyé ìlànà àti gbèdéke àkókò tó níṣe pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ gbígbà náà, àwọn ìṣe MHHS ṣàyẹ̀wò ìṣẹ̀lẹ̀ àìsanwó, àti

àwọn ìgbésẹ̀ tí MHHS gbọ́dọ̀ gbé láti pinnu tí aláìsàn kan bá yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

2. Òfin yìí ṣàlàyé bí MHHS tí ń bá àwọn aláìsàn sọ̀rọ̀ nípa iyé owó tó yẹ fún àwọn iṣẹ́ tí MHHS ń pèsè.

3. MHHS yóò tiraka láti dá àwọn aláìsàn tó le yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó mọ̀.

4. Òfin yìí tún túmọ̀ irú ipò èyítí MHHS le pa àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsàn rẹ́ láì sanwó mọ́ àti ìlànà láti darí àti láti tọpinpin pípa àwọn ìyókù àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsàn kan rẹ́.

5. MHHS kò ní ṣàmúlò Àwọn Ìṣe Gbígbà Ní Ọ̀nà Ọ̀tọ̀ bí a ti kọsílẹ̀ nínú Abala 501(r) ti Kóodù Owó Àgbàwọlé Abẹ́lé àti àwọn ìlanà òfin tí ó tẹ̀lé e.

6. Àwọn òfin àti ìlànà tí a sọ wọ̀nyí ni ó gbọ́dọ̀ bá òfin àti ìṣedédé ti ìlú Texas mu, Abala 501(r) ti Kóòdù Owó Agbawọlé Abẹ́lé, àti ìlànà tójọra.

7. Àṣẹ olúborí láti pinnu bóyá MHHS ti gbé ìgbésẹ̀ tó dára láti pinnu àmúyẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó wà pẹ̀lú MHHS.

**<u>ÀWỌN KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ ÀTI ÌTÚMỌ̀:</u>**

1. *Ìwé Ìbèrè:* Ìwé Ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní aláìsàn kan gbọ́dọ̀ fọwọ́sí.

2. *Àkókò Ìwé Ìbèrè:* Ní Àkókò Ìwé Ìbèrè, MHHS yóò gbà yóò sì ṣiṣẹ́ lórí ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àkókò Ìwé Ìbèrè bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ tí a pèsè ìtọ́jú fún ẹnìkan ó sì parí ní ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì ìwé ìdíyelé àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú náà.

3. *Ìparẹ́ Gbèsè:* Ìṣàtúnṣe sí àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsàn fún iye owó tí a rí wípé a kò le rígbà mọ́, ṣùgbọ́n aláìsan náà ní agbára láti san ìyókù owó náà. Ìpinnu yìí dá lórí lílo àmúyẹ gbígbà tó fìdímúlẹ̀ a sì ń ṣeé nìkan lẹ́yìn tí a ti díyelé àkọ́ọ́lẹ̀ kan tí a sì ti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó dára fún gbígbà.

4. *Ìṣàtúnṣe Àdéhùn:* Ìṣàtúnṣe kan tí a firánṣẹ́ sínu àkọ́ọ́lẹ̀ aláìsàn kan láti ṣàfihàn ìyàtọ̀ láàrín àpapọ̀ ìdíyelé aláìsàn ní ìpín tó fìdímúlẹ̀ àti iye tí a ń retí láti sanpadà gangan láti ọ̀dọ̀ àwọn olùsanwó míràn sí àwọn ìṣedédé tó bá òfin mu tàbí àwọn ìṣètò àdéhùn.

5. *Àwọn Ìṣe Gbígbà Ní Ọ̀nà Ọ̀tọ̀ ("ECAs"):* Èyí ni àwọn ìṣe gbígbà tó' nílò ìlànà iṣẹ́ òfin àti ti adájọ́, ó sì tún le kan àwọn iṣẹ́ míràn bíi títa gbèsè fún ẹlomíràn tàbí jíjábọ̀ àlàyé tó léwu sí àwọn aṣojú kírẹ́dìtì tàbí ilé-iṣẹ́. **MHHS kò ṣàmúlò ECAs, bẹ́ẹ̀ni kò gba àwọn aṣojú gbígbà rẹ̀ láti ṣàmúlò ECAs.**

6. *Ìrànlọ́wọ́ Owó:* Ìrànlọ́wọ́ Owó túmọ̀ sí ìrànlọ́wọ́ tí MHHS ń fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún àwọn amúyẹ owó kan pàtó àti àwọn ohun àmúyẹ míràn bí a ti túmọ̀ nínú FAP láti ràn

wọ́n lọ́wọ́ láti gba àwọn ohun àmúlò owó tó ṣe pàtàkì láti san fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtakì fún pàjáwìrì tàbí ti ìlera èyítí MHHS ń pèsè. Àwọn aláìsàn tó yẹ le kan àwọn aláìsàn tí kò ní ètò ìdójútòfò, àwọn aláìsàn tí owó-àpawọlé wọn kéré, àti àwọn aláìsàn tó ní ààbò díẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò le sanwó díẹ̀ tàbí gbogbo àwọn ìdíyelé ìlera wọn tó kù. Ìrànlọ́wọ́ owó kò níṣe pẹ̀lú àwọn owó àjẹmọ́nú àdéhùn pẹ̀lú àwọn ilé-iṣẹ́ adójútòfo àti ààbò ìlera míràn.

7. *Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán ("PLS"):* Ìsọníṣókí tódán mọ́rán ti FAP pẹ̀lú: (a) àlàyé díẹ̀ ti àwọn ohun àmúyẹ àti ìrànlọ́wọ́ tí a ń fúnni; (b) àkójọ ti ojúlé wẹ́ẹ̀bù àti ibi tí wọ́n wà tí a ti le gba àwọn ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó; (c) àwọn ìtọ́ni lórí bí a ti le gba ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ ti FAP; (5) àlàyé olùbásọ̀rọ̀ fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìlànà ìbéèrè; (6) wíwà nílẹ̀ fún ìtúmọ̀ èdè ti FAP àti àwọn ìwé míràn tójọra; àti (7) gbólóhùn ijẹ́rìísi pé àwọn aláìsàn tí a pinnu pé wọ́n yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní díyelé ju iye owó tí a ń bèrè fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì.

8. *Àwọn Ìgbésẹ̀ Tó Ní Ìtumọ̀:* MHHS yóo gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó ní ìtumọ̀ láti pèsè àlàyé fún aláìsàn nípa FAP ti MHHS nípa fífún àwọn aláìsàn ní Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán ti FAP ní ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ àṣehàn ti iṣẹ́ náà. Ní àfikún, MHHS yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wífún àwọn aláìsàn nípa FPA ti MHHS.

   a. *Àwọn Ìwé Ìbèrè Tí Kò Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí bá fa ìwé ìbèrè tí kò péye kalẹ̀, lẹ́yìn náà MHHS yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé àkọsílẹ̀ tó nílò.

   b. *Àwọn Ìwé Ìbèrè Tó Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí mọ̀lẹ́bí aláìsàn náà bá fa ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó tó péye kalẹ̀, MHHS yóò pèsè ìfitónilétí àfọwọ́kọ tí ń sọ nípa ìpinnu yálà aláìsàn náà yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní àkókò tó yẹ yóò sì sọ fún aláìsàn náà ní kíkọ nípa ìpinnu (pẹ̀lú, tó bá yẹ, ìranlọ́wọ́ fún èyítí aláìsàn náà yẹ fún) àti àwọn ìdí fún ìpinnu yìí. Ìfitónilétí yìí yóò tún pẹ̀lú iye ìdá ọgọ́rùún Ìrànlọ́wọ́ Owó (fun àwọn ìwé ìbèrè tí a fọwọ́sí) tàbí (àwọn) ìdí fún sísẹ́, àti iye owó sísan tí a ń retí lọ́wọ́ aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí tó bá wà. Aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí yóò máa gba àkọsílẹ̀ owó ní àkókò àyẹ̀wò ti ìwé ìbèrè tó parí.

   c. *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn:* MHHS yóo fi oríṣìí àkọsílẹ̀ owó ránṣẹ́ tí ń ṣàlàyé àkọọ́lẹ̀ aláìsàn àti iye tó yẹ láti san. Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wífún MHHS nípa wíwànílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, àkíyèsí FAP ti MHHS, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé àkọsílẹ̀ FAP.

   d. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHHS:* Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSS yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì tí Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHHS yóò ṣàgbéjáde FAP náà pẹ̀lú àkójọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, ìsọníṣókí èdè tódán mọ́rán, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Gbígbà àti Ìdíyelé lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti

MHHS: http://www.memorialhermann.org/financialassistanceprogram/. MHHS yóò ní àwọn ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀.

**ÀMÚYẸ ÀTÚNYẸ̀WÒ:**

1. *Bíbá Aláìsàn Sọ̀rọ̀:* Ní ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ owó àpawọlé, àwọn aláìsàn yóò gba ìbánisọ̀rọ̀ àfẹnusọ tàbí àkọsílẹ̀ nípa ìyókù owó wọn, àti àwọn ìrètí ìsanwó MHHS. Gbogbo ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú aláìsàn yóò pẹ̀lú àkíyèsí nípa wíwà nílẹ̀ FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ láti pè fún àfikún àlàyé, àti àdírẹ́sì ojúlé wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ẹ̀dà FAP àti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tójọra. MHHS yóò fúnni ní ẹ̀dà Ìsọniṣókí Èdè Tódán Mọ́rán ti FAP sí gbogbo òbí.

    a. Àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò ni a rétí kí wọ́n sowọ́pọ̀ pẹ̀lú MHHS nínú ìtiraka rẹ̀ láti dá àwọn orísun owó mọ̀ nípasẹ̀ àwọn ètò ìjọba ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ láti yanjú àwọn ìnáwó ìtọ́jú ìlera wọn. Àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò yóò gba àkọsilẹ̀ owó oṣoṣù èyítí ń ṣàlàyé FAP náà, àti iye owó wọn tókù tí ó tó ọjọ́ 150 ṣàgbéjáde déètì iṣẹ́ náà.    Tí aláìsàn kan bá kùnnà láti wọ inú ètò ìsanwó kan lọ tàbí yanjú ìyókù gbèsè wọn MHHS yóò ṣàyẹ̀wò fífi àkọ́ọ́lẹ̀ náà ṣọwọ́ sí aṣojú gbígbà míràn.

    b. Àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò ni a retí kí wọ́n ṣowọ́pọ̀ pẹ̀lú MHHS nínú ìgbìyànjú rẹ̀ láti gba àwọn ìsanwó láti olùṣe ìdójútòfò aláìsàn náà. Ó tún gbọ́dọ̀ yé aláìsàn pé nígbàtí MHHS bá díyelé olùṣe ìdójútòfò aláìsàn ó jẹ́ ìlànà iṣẹ́ èyí kò sì ṣèmúkúrò ojúṣe owó ti aláìsàn láti sanwó fún àwọn iṣẹ́ tí MHHS pèsè. Nítorí náà, nígbà míràn MHHS yóò bèrè kí aláìsàn kan sowọ́pọ̀ pẹ̀lú olùṣe ìdójútòfò rẹ̀ láti yanjú ìdádúró ìsanwó tàbí yanjú àwọn ìṣòro ìṣàkóso míràn èyítí ń dènà ìsanwó fún iṣẹ́ míràn.  Kété tí MHHS bá ti gba owó fún àwọn iṣẹ́ tí a sì ti ṣàmúlò àwọn ìṣàtúnṣe àdéhùn tó dára sí àkọ́ọ́lẹ̀ náà aláìsàn náà yóò gba àkọsílẹ̀ owó oṣoṣù èyítí ń ṣàlàyé FAP àti iyókù owó tí ó tó ọjọ́ 120 lẹ́yìn ìsanwó olùṣe ìdójútòfò. Tí aláìsàn kan bá kùnnà láti wọ inú ètò ìsanwó kan lọ tàbí yanjú ìyókù gbèsè wọn MHHS yóò ṣàyẹ̀wò fífi àkọ́ọ́lẹ̀ náà ṣọwọ́ sí aṣojú gbígbà míràn.

2. *Ìrànlọ́wọ́ Owó:* Ó jẹ́ ìṣe MHHS láti ran àwọn aláìsàn lọ́wọ́ láti rí owó gbà láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹlòmíràn. A ó pèsè ìmọ̀ràn ìṣúná owó láti ran àwọn aláìsàn lọ́wọ́ láti mọ àwọn ètò ààbò ìtọ́jú ìlera ti ìjọba ìpínlẹ̀ tàbí àpapọ̀ èyí tó le wà nílẹ̀ fún wọn, àti láti pinnu àmúyẹ lábẹ́ FAP náà. Ìṣẹ́ gbígbà ni a ó dádúró fún ìgbà díẹ̀ títí di àbájáde àwọn ìpinnu wọ̀nyí, ṣùgbọ́n àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn ni a ó máa firánṣẹ́. Fún Ìrànlọ́wọ́ Owó nípasẹ̀ MHHS, àmúyẹ tí a ń lò láti ṣírò iye ẹ̀dínwó, àwọn ìgbésẹ̀ tí MHHS yóò gbé láti polongo FAP náà láàrín àdúgbò tí MHHS ti ń ṣiṣẹ́, ìlànà iṣẹ́ tí MHHS lò láti pinnu ìmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti ìlànà iṣẹ́ ìbèrè náà ni a ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ nínú **MHHS Financial Assistance Policy.**

3. *Àwọn Ètò Ìsanwó:* MHHS ń fún àwọn aláìsàn tó ní ìṣòro láti sanwó fún ìdíyelé wọn ní àwọn ètò ìsanwó tó gùn, tí kò sì ní owó àsanlé. Àwọn aláìsàn le bẹ̀rẹ̀ ètò ìsanwó kan nípasẹ̀ Ààyè Aláìsàn San Gbèsè Mi (https://paymybill.memorialhermann.org/?_ga=1.221977755.265979238.1484666437). A ó bèrè lọ́wọ́ àwọn aláìsàn láti sanwó oṣoṣù ó kéré jù láti tọ́jú ètò ìsanwó tí ń ṣiṣẹ́. Tí aláìsànkan bá kùnnà láti sanwó bí a ti ṣètò a ó rí aláìsàn náà bíi ọ̀daràn lórí ìlérí tí wọ́n ṣe láti sanwó fún gbèsè inú àkọ́ọ́lẹ̀ wọn. A ó gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó dára láti tún fi ìdí ètò ìsanwó aláìsàn kan múlẹ̀ nípa títẹ̀lé ìsanwó ọ̀daràn àkọ́kọ́. Tí aláìsàn kan bá kùnnà láti tún fi ìdí ètò ìsanwó kan múlẹ̀ àti/tàbí tí ó di ọ̀daràn fún ìgbà ìkejì MHHS yóò fi àkọ́ọ́lẹ̀ náà ṣọwọ́ sí aṣojú gbígbà míràn. Kété tí a bá fiṣọwọ́ sí aṣojú gbígbà míràn aláìsàn náà yóò ní láti ṣiṣẹ́ papọ̀ tààrà pẹ̀lú aṣojú míràn náà láti yanjú gbesè wọn tó kù. Aláìsàn náà kò ní ẹ̀tọ́ láti wọ inú ètò ìsanwó míràn lọ nípasẹ̀ MHHS, Ààyè Aláìsàn Ìdápé Ojojúmọ́ fún àkọ́ọ́lẹ̀ pàtó náà. Ṣùgbọ́n, aláìsan náà yóò lẹ́tọ̀ọ́ láti fìdí ètò ìsanwó kan múlẹ̀ fún àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ míràn nípasẹ̀ Ààyè Aláìsàn Ìdápé Ojojúmọ́ náà.

4. *Àwọn Ìṣẹ́ gbígbà tí A Kò Bá Sanwó:* Tó bá wáyé pé ẹnìkan kò sanwó, a ó ṣàmúlo oríṣìí iṣẹ́ gbígbà èyí tó dá lórí ìyókù owó, gbèsè àsanpadà olùsanwó ẹlòmíràn, àmúyẹ aláìsàn fún owó ìjọba tàbí Ìrànlọ́wọ́ Owó, ìsowọ́pọ̀ aláìsàn, ìtàn ìsanwó tàbí gbèsè, àti/tàbí àìle rí aláìsàn náà. Àwọn iṣẹ́ gbígbà le pẹ̀lú ẹ̀bẹ̀ sísẹ́ olùsanwó ti ẹlòmíràn; ìbánisọ̀rọ̀ láti ṣàbẹ̀wò pẹ̀lú olùsanwó ẹlòmíràn; àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ owó, lẹ́tà, àti àwọn ìpè lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ sí aláìsàn tí ń fúnni ní Ìrànlọ́wọ́ Owó ati/tàbí bíbèrè ìsanwó, àti ìfitónilétí tó parí sí aláìsàn náà tàbí olùfọwọ́sọ̀yà pé àkọ́ọ́lẹ̀ náà ti dáràn ó sì yẹ kí a fifún aṣojú gbígbà tí kò gbọ́dọ̀ pẹ́ ju ọjọ́ 120 lọ láti déètì àkọ́ọ́lẹ̀ owó àkọ́kọ́ tí a wífún aláìsàn tí iye owó tí aláìsàn náà jẹ.  A tún le bẹ̀rẹ̀ ìṣe òfin nípasẹ̀ MHHS sí ẹlòmíràn tó yẹ (gbèsè ẹlòmíràn) fún ìsanwó ọ̀daràn ti àkọ́ọ́lẹ̀ náà.

5. *Gbèsè àìlè san padà:* A le pa àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ kan rẹ́ sí gbèsè tí a kò le san padà pé a ti díyelé àkọ́ọ́lẹ̀ náà pátápátá sí (àwọn) olùsanwó ẹlòmíràn àti sí aláìsàn/olùfọwọ́sọ̀yà, ìdíyelé tí a fìdímúlẹ̀ àti àwọn ìbánisọ̀rọ̀ àbẹ̀wò ti wáyé, a sì tí gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó péye láti sọ fún aláìsàn nípa wíwà nílẹ̀ ti Ìrànlọ́wọ́ Owó, àkókò ìsanwó sì ti dópin, tí a sì ti pinnu wípé a kò le rí owó náà gbà padà mọ́.

6. *Àwọn Ìṣe Gbígbà Òde:* Láti ṣàrídájú wípé àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ tó lẹ́tọ̀ọ́ nìkan ni a parẹ́ sí gbèsè tí a kò le rígba mọ́, àti wípé lẹ́yìn tí a ti gbé àwọn ìgbésẹ̀ ìdíyelé àti gbígbà, pẹ̀lú ìtọ́kasí tó dára sí ilé-iṣẹ́ òde fún gbígbà, ẹgbẹ́ Iṣẹ́ Oníbààrà yóò ṣàyẹ̀wò ìparẹ́ àwọn gbèsè tí a kò le rígbà fún ìfọwọ́sí. Lílo àmúyẹ gbígbà tí a fìdímúlẹ̀ àti àwọn òdíwọ̀n àṣẹ ìparẹ́ tí a fọwọ́sí, Adarí Iṣẹ́ Oníbààrà le yálà fọwọ́sí píparẹ́ náà tàbí gbà níyànjú ìṣe tó dára sí Ìgbákejì Àrẹ ti Ìṣàkóso Owó Àgbàwọlé. Àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ ni a tún le fiṣọwọ́ ní aládàáṣe sí ilé-iṣẹ́ òde fún gbígbà nípasẹ̀ ìlànà ìṣírò aláìsàn náà, èyí tó dá lórí olùsanwó to fẹsẹ̀múlẹ̀, ìyókù owó, àti àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ ìsanwó.

7. *Ìmúṣiṣẹ́:* Ó jẹ́ ojúṣe ti MHHS Ẹ̀ka iṣẹ́ Ìṣàkóso Owó Àgbàwọlé láti mú òfin yìí ṣiṣẹ́ kó sì ṣàmúgbòrò àwọn ìlànà iṣẹ́-ṣíṣe pàtó ti ẹ̀ka iṣẹ́.

**ÀWỌN IBI ÌTỌ́KASÍ:**

A. Òfin Ìfiṣọwọ́ Aláìsàn (EMTALA àti Ìfaramọ́ Òfin Ìfiṣọwọ́ Ìlú Texas)
B. Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó
C. Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán Ìrànlọ́wọ́ Owó
D. Ìwé Ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó